ary 11, The Chief Secretary to the Govt

**Dada Adeshigbin Memorial Number.**

# EKO AKETE.

"EMI YIO FI OHUN TI O NDUN MAKUNNU HAN AWON ALAGBARA, NGO SI JE ALAGBAWI AWON ODI."—W. T. STEAD.

VOL. VI. No. 261 SATURDAY, FEBRUARY 11, 1928. 4d.

The Leading Weekly Vernacular Newspaper in Nigeria.

23 FEB 1928

**White's Radical Gonkiller.**

:o:

(NATIVE.)

[*A complete cure for old and fresh Gonorrhoca.*]

When Gonorrhea is not properly cured, it gives rise to other troubles and diseases, such as Barreness, Piles, Kidney Diseases, Stricture, Rupture, Rheumatism, Sore-eyes, etc.

N.B.—This Medicine cures Gonorrhea completely in either man or woman, so that no secondary diseases can follow.

Made from pure **Native Herbs,** and sold only by VICTOR WHITE, ESQ., *Chemist.*

41, Offin Road, Lagos.

PRICE: Ten Shillings (10/-) per bottle.

*Packing and Postage 2/6d. extra, to all parts of Nigeria.*

EGBOGI ALAWOTAN ATỌSI.

:o:

[*Fun Atọsi lailai ati titun.*]

Ti a ko ba tete wo Atọsi san daradara, o ma ndi enia lọwọ lati ṣe abiamọ, o si ma nfa oriṣi arun mi wa, bi:—Jẹdi-jẹdi, Aran, Iju, Ẹda, Ipake, Ase, Lakuregbe, Arun Oju, ati arun mi.

*N.B.*—Egbogi yi nwo Atọsi san lawotan patapata, ko si njẹ ki o ri aye wu arun mi silẹ.

"AWA O MA JO, AWA O MA YỌ, NI"

Aga ati Asia (*Flags*) ti Germany lorişirişi wa fun hihaya ni No. 3, Docemo Street, Lagos. Aga ati Asia wọnyi dara fun akẹkẹyẹyẹ pupọ, fun Igbeyawo Wolimọ, Ijọ-Ọdun Musulumi, tabi ti Kiriyo, fun ere nile Ẹgbẹ, ati orişirişi ohun ayọ miran.

*Terms very moderate*

for particulars, please apply at :—

EKO-ATỌRO CHAIRS & FLAGS SUPPLY

*Office* :—

No. 3, Docemo Street,
P.O. Box No. 505.
Lagos, Nigeria.

---

**Coffins to suit your Taste.**

Coffins with Pillows, Shroud, Brass Edges, and Removable Lids, on sale at J. B. da Silva, 40, Odunlami Street, Lagos: also Gramophone Records, Gas-lamps, etc., etc.

Prices to suit you. No worry, prompt attendance. Make a call.

---

## Ero ya wa ra

ADEBOYE ŞOLANKẸ Onişowo "Gbabiọgẹdẹ" nta Panu-kikọle ati kikan-ọkọ, Işo lorişirişi, Kọkọrọ (Işika) t'ilẹkun ati t'apoti lorişirişi, Atupa fifalọwọ, Simẹnti, Ọda lorişirişi ati Epo-ọda, Fikifiki, Okun ẹrọ, ati Ọşan, ati Pakun ti Awo-ẹja lorişirişi, Awo ti awọn Aganyin fi nko Ẹja-şawa l'okun ati Ẹja Abọmafọ, ni Şọbu rẹ ni No. 4, Idunmagbo Street, (l'ebute Olowu) ati ni No. 19, Moloney Bridge Street, (l'Anikantamọ) l'Eko.

O nta Iworo (Golu) ati Fadaka-tutu ati Irin-işẹ Agbẹdẹ Iworo ati Fadaka.

**Owo Ọja rẹ fanimọra. Ẹ lọ ra tiyin nibẹ.**

---

**Are you a Mechanic ?**—If so you must want Tools, now or soon!

**Do you intend to put up a house ?**—Then you will require Builder's Hardware!

In either case you cannot do better than call at

## *B. C. Vaughan's "Excelsior" Stores*

at Agarawu Street, Lagos.

Where the largest and most varied assortment of Artisan's Tools and Building Materials in Lagos is stocked.

Quality to satisfy all demands, and prices to suit all pockets.

*Special discount to Traders and Wholesale buyers.*

---

## *J. C. VAUGHAN*

Ti ile ọja Sheffield ni ita Kakawa ati ile-ọja *Excelsior* ni ita Agarawu ni orişirişi ati oniruru ohun kikọ 'le fun tita ni owo-ọpọku-ọyọku.

Ilẹkun awọn ile-owo mejeji wọnyi şi silẹ fun awọn Ọmọle ati awọn Gbẹnagbẹna : bi o fẹ da awo ni o, ero-ija dida'wo ko ni jẹ ọ ni'ya lati ra nibẹ :

Alagbẹdẹ Wura tabi ti Fadaka ni ọ ni o, gẹgẹ l'oşe fun ọ lati re yan irin-işẹ tirẹ nibẹ ba kanna

Owo Ọgbẹni J. C. Vaughan ti di Owo Atari-Ajanaku lọjọ to ti pẹ : bi Ọgẹdẹ si ni Owo rẹ ngba kakiri ibikibi. Agbẹ ni ọ kai ! bi o ri orişirişi Ọkọ ti o ri ra nibẹ ha yio şe ọ.

Sure tete iwọ Ọmọle, iwọ Gbẹnagbẹna, iwọ Aranbata, iwọ Asenjẹ iwọ Ageginigbo (*Sawyer*) Alagbẹdẹ Wura, iwọ Alagbẹdẹ Fadaka, iwọ Agbẹ re ba ori're tirẹ pade nibẹ.

**Owo-lọwọ ni gbogbo ọja meremere ibẹ.**

*Editor & Proprietor:—*
ADEOYE DENIGA
*Office* 24, Williams Street,
Lagos, Nigeria.

ASAN-SILẸ NI OWO GBIGBA RẸ.

| | Eko. | Ilu miran ni Nigeria. | Ilu Okere |
|---|---|---|---|
| Ọdun kan | 12/- | 13/- | 14/- |
| Oṣu mẹfa | 6/- | 6/6d. | 7/- |
| Oṣu mẹta | 3/- | 3/6d. | 4/- |

Ẹ fi owo ati *Letter* ranṣẹ si *Editor*.

## GBOHUN-GBOHUN.

### OGO NGO-NI-FILA!

Pẹkirẹki ni a ṣalabapade ọgọrọ awọn Ọlọpa ni *Monday* ọsẹ yi ti awọn ti fila titun ti nwọn ṣẹṣẹ nde nisisiyi, ko si bo ti ri ni giga fila na, o yẹ wọn gidigidi, a ki Ijọba, papa awọn Olotu Ọpa Ọba wọnyi ku na'wo o!!

### ỌYẸ A-MUKARA GB'ODE.

Lati ẹnu ọsẹ to koja ni ọyẹ ti mu a-mukara ti o si ka pupọ enia lara bi ãṣa-imu, o tilẹ fẹrẹ di otutu atinu-wa fun awọn ẹlomiran gẹgẹbi a ti gbọ iro na si; ki Baba maṣai jẹ ki mimu ọyẹ ọdunni ṣe olukuluku lore. Amin.

---

### TRANSFER OF MR S. O. OSIYALE TO ST. ANDREW'S COLLEGE, OYO.

An unexpected appointment of a College Tutor at St. Andrew's College, Oyo was offered to Mr. S. O. Osiyale, the Headmaster of Holy Trinity Ebute Ero School, Lagos.

This gentleman is an energetic Teachers educated at the College.

We wish him good luck and success in his new sphere of work.

---

### CHANGE OF NAME.

S. A. COLEMAN-DANIEL
TO
ADENIJI ṢOYỌMBỌ-ABỌWABA.

Commencing from the 1st day of February, 1928, the public are hereby notified that I, formerly known as S. A. Coleman-Daniel, do now desire to be known and called by the name

ADENIJI ṢOYỌMBỌ-ABỌWABA.

All documents bearing my former name remain valid

## ITAN IGBESI-AIYE



### DADA ADESHIGBIN,

ẸNITI O JẸ IPE OLODUMARE NI ỌJỌ KẸJỌ (SUNDAY) OṢU FEBRUARY, 1925.

Lati ọwọ EDITOR EKO AKETE.

"Ewe ni akoko rirẹ wọn,
"Awọn itanna si ni akoko ati rẹ;
"Awọn irawọ pẹlu si ni akoko wiwọ wọn;
"Ṣugbọn, A! iwọ ni gbogbo akoko fun 'ra rẹ—Iku!
MRS. MARY HEMANS.

### IBI RẸ

A bi Dada Adeshigbin ni Abẹokuta ni iwọn ọdun 1865 li Itun Ago Owu, ọdun mẹta lẹhin iku Ọba Okukẹnu, Alake kini ti o kọ jẹ ni Abẹokuta, diẹ li a mọ nipa itan igba ewe rẹ, titi o fi to bi iwọn ọmọ ọdun mẹrindilogun, ti o bẹrẹsi lọ si Ile Ẹkọ ti St. Paul's (Breadfruit) ni ilẹ yi, on pẹlu awọn ọmọde miran ti o wa ni sa rẹ, lẹhin ti awọn obi rẹ—Adeṣigbin baba ati Adeọla Layẹni iya rẹ ṣipo pada lati Abẹokuta wa si Eko.

Dada Adeşigbin jẹ abami ọmọ, nipa irun ori rẹ ti o pọ şikiti, nigbati a bi i, o jẹ arẹwa ọmọ ti o dara, eyi li o si jẹki a fun u ni orukọ Dada ti a fi npe e, nitoripe gẹgẹbi orukọ ilẹ Yoruba, ọmọ ti a ba bi pẹlu irun ori pnpọ bẹ ni a npe ni Dada, fun apẹrẹ, ọmọ ti a ba bi ni isojude ni a npe ni Ajayi; awọn ti a ba bi pẹlu okun-ibi ti o kọ wọn lọrun lọtun losi ni a npe ni Ainọ. Awọn ti a si bi ni fifi iha le 'lẹ ni a npe ni Ojo. A bi Adeşigbin baba rẹ ni akoko gan ti a ya ilu ti a npe ni Igbin sọtọ fun isin Ọbatala; nitori itumọ orukọ yi ni "ẹniti o wa lati wa şi ilu ti a npe ni Igbin," eyini ni pe, ọmọ ti a bi ni ọjọ na gan, nigbati a o ya ilu Ọbatala yi sọtọ.

## AKOKO RẸ NI ILE ẸKỌ.

Biotilẹşepe balogun wa ti a nsọ itan rẹ yi ko tilẹ ni ni anfani Ile Ẹkọ Giga, sibẹ ko jafara lati mura si ati kọ iru ẹkọ ti a şe ipese tun ni Ile Ẹkọ olokiki ni St. Paul's Breadfruit, Ile Ẹkọ olokiki, nitoripe ibẹ ni ọja ẹru ni akoko ti owo ẹru pẹlu awọn Oyinbo ti o nti Oke okun wa wa lode. Oniruru ni itan ti ologbe ima pa fun wa, nipa Ọgbẹni E. E. Collins—Tẹla Adebiyi, nigbati o nşe oluko wọn nipa oniruru ọna ti o ngba fẹ awọn ọmọ Ile Ẹkọ ni iya, iru iya eyiti, bi o ba şepe labẹ ofin akoko yi (The Criminal Code) ni, ọpọlọpọ olukọni ni iba ti lu pupọ ninu awọn Ofin wọnyi. Ni akoko ti o wa ni Ile Ẹkọ, a sọ pe imọ rẹ ninu Ẹkọ ti a npe ni Jeografi (Geography) pọ tobẹ ti a fi npe e ni "Dardanelles"—orukọ omi toro kan, ti o wa li agbedemeji omi Gulf of Salonika ati Strait of Gallipoli ti ko ju iwọn isọko kan ni jijin si awọn ọwọ erekuşu kan ni Okun Aegean ni ebute Okun Adriatic, ni Gusu Europe (Ilu awọn Oyinbo). Ọpọlọpọ ninu nyin si le ranti ọpọlọpọ awọn ọmọ ogun ti o ku si ibi yi ni akoko Ogun Ajakaiye ti o şẹlẹ laipẹ pupọ yi, eyiti a si sọrọ pupọ nipa rẹ lakoko na ni Ajọ Igbimọ nla ti a şe ni ilu Gẹsi.

## LI ẸNU IŞẸ.

Lẹhin ti o fi Ile Ẹkọ silẹ, o ko işẹ aşọ-riran labẹ Ọgbẹni Antoninus King (Ologbe), Ọga Tailor, ti o lokiki fun mimuna ati mimọ işẹ aşọ-riran.

## IŞẸ ŞIŞE ŞIWAJU IGBADUN,

Lẹhin ti o mọ işẹ tan, tabi lẹhin ti o "firi," gẹgẹbi a ti ima wi, o bẹrẹ işẹ aşọ riran fun ara rẹ. Awọn ọrọ wọnyi si ni awọn ọrọ rẹ—"Işẹ şişe şiwaju Igbadun." O si ni asiki tobẹ lẹnu işẹ yi nigbana tobẹ lati ibẹrẹ kekere ni ibiti a gbe nta Maşini (Singer Sewing Machine) loni, ti o si di ọkan ninu awọn Tailor olokiki ni sa rẹ. Ki şe pe ohun gbogbo lọ daradara fun u nigbana li aisi ikọsẹ, şugbọn a dupẹ pe, fun ire ara rẹ lẹhin na, o kọ, o si mu awọn ọrọ wọnyi, ti alarofọ Mautua ni sọ pe:—

Işẹ l'adun, o si wulo,
Bi o tilẹ burẹwa, ti o si l'oro bi ọpọlọ,
O ni işura iyebiye lori rẹ.

Lakoko kan, niwọn ọdun mejidilọgbọn ọh mba şọja kan, ara ilu West Indies şọrẹ. O awọn ẹlẹgbẹ rẹ ti işe ara ilu kanna ngbe ibiti Glover Memorial Hall si nisisiyi ọrẹ rẹ yi ti di "korikosun" rẹ (Fidus Achates),—aworan a şi le ri nisisiyi—ni o şe itanlọwọ fun u tailor (onişona) pataki fun awọn ẹgbẹ ọmọ ti a npe ni West Indian Regiment, ti a sọrọ Dajudaju, apẹrẹ ọrẹ totọ li eyi, iru eyiti a le ọrọ ti Shakespeare fi si ẹnu Polonius lati Laeretes ọmọ rẹ sọ we:—

"Awọn ọrẹ ti o ni, ti o si ti danwo,
Fi iwọ irin di wọn mu şinşin"

Nigbati o şe, ọrẹ wa di Agent ni gbogbo Nigeria fun awọn ẹgbẹ ti o nta Maşini—Singer Sewing Machine Company ti ilu Amẹrika. Ni akikanju lẹnu işẹ ati olotitọ enia ti o jẹ, o ẹniti o nşe Agent yi fun wọn, titi o fi tẹri gba Ni gbogbo akoko ti o fi şe işẹ yi, ni a gbọ rẹ jakejado igun mẹrẹrin aiye. O fi ayan ọpọlọ şe işẹ awọn ọga rẹ tobẹ ti Gomina Sir Walter Egerton ti o şe Gomina ilẹ yi ni ọdun 1910 fi ọkan ninu awọn onibara rẹ.

"Iwọ ri enia ti nfi aişemẹlẹ şe işẹ rẹ? On duro niwaju awọn ọba; on ki yio si duro niwaju awọn enia lasan."—Solomon (Owe 22 29.)

## ALMANAKI RẸ TI IMA ŞE.

Ko ni isimi si gbogbo eyi nikan. Şugbọn wa tun sun orukọ awọn ọga rẹ siwaju nipa almanaki lọdọdun eyiti aworan awọn enia ninu enia dudu ima yọ, (ọkọkan lọdun)—aşa bẹrẹsi şakiyesi lati igba ti ologbe Ọgbẹni Robert Antus Williams ti di Agent T. W. Longe & Co Nipa bayi, ọrẹ wa nşe iranlọwọ nlanla nipa rẹ bayi lati jẹki ọpọlọpọ enia ma ri ẹkọ kọ nipa enia nla wa wọnyi, ti o ti simi ninu lala Inu wa si dun lati kiyesi pe awọn Olutọju ile Glover Memorial Hall fi inudidun gba meji awọn aworan wọnyi. Nitotọ,

"Ope ni egun awọn orişa,
Imọ si ni iyẹ, ti a fi nfo lọ si ọrun."
Shakespeare

## INUDIDUN RẸ LATI MA RAN ẸLOMIRAN LỌWỌ.

Ẹmi aimoti-ara-ẹni-nikan ti ọrẹ wa ni nfarahan nipa bi ti ima fi aniyan yara ran ẹlomiran lọwọ yala nipa owo, tabi li ọna miran. Ẹniti a nsọrọ nipa igbe aiye rẹ yi ko le dupẹ lọwọ rẹ to fun inurere ti ko lẹgbẹ ti ologbe fihan si i, nipa Magic Lantern rẹ, ti o mbà a ya li akoko, ti o nsọrọ nigbangba nipa awọn Olokiki ninu awọn Enia Dudu

Noted Africans ) ti o ti ku, ati eyiti o si wa. Ki ise eniti nsọrọ yi nikan ni ọrẹ wa nṣe iru anlọwọ bayi fun, ṣugbọn fun ọpọlọpọ bẹ, ati gbajọ enia pẹlu, ti o nfi inudidun ṣe iru iranlọwọ fun lọfẹ ati laigbowo. Gbọ ẹri ti ẹnikan ti o owe sinu Iwe Irohin—*The Lagos Weekly Record* ti ọjọ 7 de 21, oṣu April, ọdun 1923 jẹ pa rẹ:—

MR. DADA ADEṢHIGBIN.

Bọkini yi jẹ ọkan ninu awọn Alagba diẹ ti a ni, o farabalẹ, ti o si ni ifẹ ilu rẹ lọkan; on ki isi iṣe awọn ẹlomiran ni ilẹ yi, ti o lowo ṣugbọn ti wọn ko ni ọgbọn lori, ti ima ṣe nipa fifi ẹnu fun fere ara wọn kiri.

Niwọn ipari ọdun 1922, Ọgbẹni Dada Adeṣigbin fi owo ara rẹ rin kakiri ilẹ wa fun ire Ijọ o jẹ mẹmba rẹ, nibigbogbo ti o si de ni o nfi Magic Lantern rẹ mu awọn enia laraya, eyiti o unmọ Oni, Ọba Ile Ifẹ ibiti itan atọwọdọwọ ilẹ Yoruba pe ni ibiti gbogbo araiye ti ṣẹ.

NIFẸ ILU RẸ TI KO FUN FERE ARA RẸ.

O jẹ enia jẹjẹ, ti ko fẹ nkan ariwo. Igbagbogbo ki si fẹ ki a polongo rẹ nigbati o ba ṣe anlọwọ ti o kun enia loju. Nipa iru ẹmi bayi ti ma fẹ ki a gbe ara ẹni han nigbangba fun ire a ṣe, o yatọ pupọ si awọn ẹlẹgbẹ rẹ miran ti o fẹ ki a mọ wọn bẹ, ṣugbọn ti nwọn ko to ni iru ti on ngbe.

"O ṣeun, iwọ olotọ ati iranṣẹ rere
Bọ sinu ayọ Oluwa rẹ".

Bi igba ti manamana kọ, bẹni iku ọrẹ wa ba ilu ojiji, ohun ti o si yani lẹnu ni pe kiki iba enia diẹ hin awọn ẹbi rẹ li o mọ pe o nṣaisan, ki titan to de. O si yani lẹnu pẹlu lati gbọ pe, bi o ti wa ni ibulẹ aisan ni, titi o fi di akoko ti o fi dakẹ jẹ, o ṣe aniyan pupọ pe ki Ẹni ọwọ Baba rẹ nipa ti Ọlọrun ti ọfọ ṣẹṣẹ ṣẹ, Alufa Alabojuto J. S. Williams tete de. Ọjọ Sunday ti o dakẹ yi ni Alabojuto yi si de lati idalẹ ibiti o ti lọ ṣe iṣẹ abojuto rẹ kakiri.

Nwọn a ma sọ—otitọ si wa ninu rẹ—pe ki ṣe ki a ma ri ohun abami kan, lọna kan tabi omiran, nigbati awọn enia ti aiye npe ni ẹni nla ba ku. Bẹ si ni nipa ti iku ọrẹ wa niwọn agogo mọkanla abọ lowurọ ọjọ isimi ti ọjọ kẹjọ oṣu February ni ọdun 1925 ni ile rẹ "Abayọmi Vlila" ni 4, Layẹni Street, l'Eko, a ṣakiyesi orun ati oṣupa, ti nwọn nja ni agogo mọkanla abọ loru ọjọ kanna, ki a to tẹ oku rẹ, iru ohun abami ti o jọ eyi, to ṣẹlẹ ni ọjọ kẹfa oṣu May ni ọdun 1910, nigbati Ọba Edward keje waja, ti o "lọ si ọuun aremabọ," pupọ ninu enyin ọrẹ wa, ti o wa nihin loni yi, boya yio ranti bi iji nla kan ti ja jakejado gbogbo, ti o si nwole pẹlu; ati nijọ keji, ti o tẹle e, bi a ti mu ihin aro na wa gbukẹ lati Oke Okun pe Ọba waja. Ẹwẹ, bakanna ni, nigbati ologbe Dr. Mọjọla Agbebi M.A. P.H D ku, ti a rohin rẹ pe a ri ami miran bẹ ni ọrun ni ọjọ 24 oṣu May, ni ọdun 1917 (Ọjọ Ibi Victoria, Ẹni rere). Obinrin alafojnri kan sọ pe, niwọn agogo mẹwa abọ lalẹ, imọlẹ kan farahan loju ọrun, ti o ndan mana, ti o si tan imọlẹ si apa ibiti ile ọgbẹni yi, ọga ninu iwe, gbe wa, a si gbọ iro ti o le di enia leti, bi iro rọkẹti, lẹhin eyiti idakẹrọrọ si wa. Ni ilu Saro, iru nkan bẹ tun ṣẹlẹ, nigbati Dr. Walmsley, Biṣọpu ibẹ ku, gẹgẹbi a ti rohin na ninu Iwe Irohin ti a npe ni Sierra Leone Weekly News ti ọjọ 23, oṣu December ti ọdun 1922.

IRAN TI ỌLỌPA KAN RI.

Si Oniwe-irohin *Weekly News.*

Ọgbẹni,

Mo tọrọ gafara fun aye diẹ lati rohin diẹ fun anfani awọn ti o gbọ, ṣugbọn ti nwọn nṣiyemeji nipa ohun ti mo ri ni kutukutu owurọ Monday ọjọ 11 oṣu December, ti ọdun 1922, ki nwọn ba le mọ ohun ti o ṣẹlẹ ni gasikia, ati bi oni gbagbọ, ki o ba le tubọ mu ki wọn ni igbagbọ ninu Ọlọrun siwaju.

Mo wa lẹnu iṣẹ ni Ile Ọlọpa ti arin Ilu. Mo lọ bẹ awọn ọlọpa gbogbo wo lẹnu iṣẹ wọn ni Ebute Ọba; bi mo si ti npadabọ wa si Ile Ọlọpa, leti Ita George (George Street), mo ri imọlẹ nla, ti o mọlẹ ninu Ṣọṣi nla (Katidrali) ti o wa nibẹ yika. Li ẹnu abawọle Ṣọṣi Nla na, mo ri ọkunrin kan duro pẹlu ago kan lọwọ rẹ, ago yi dabi iru eyiti a nlo ni akoko Ipinfunni Onjẹ Alẹ Oluwa. Imọlẹ na tan si mi loju, o si mu oju mi ṣu, mo si ngbọn. Bi mo si ti sunmọ ibẹ lati wo ohun ti o ṣe, mo ri oju ti o dabi ti Biṣọpu Walmsley ologbe na, ti a ti sin oku rẹ bi ana. Bi mo si ti yipada si ọna abalọ si Ọfisi Akọwe Ijọba (Colonial Secretary's Office), bẹni mo si ṣubu lulẹ, ti mo daku lọ, nitori imọlẹ nla yi ati aworan ẹniti mo ri yi.

Sajin (Sergeant Augustus Macfoy) li o ṣe iranlọwọ fun mi, o bu omi si mi lara, ki mba le sọji. O to wakati meji lẹhinna. Nko le sọ gbogbo bi nkan ti ri tan, ṣugbọn ohun ti o daju mbẹ ni pe ohun ti mo ri mu mi lọkan pupọ, on li o si mu ki ndaku. Eyi ni irohin otitọ nipa ohun ti mo ri.

Emi ni tirẹ nitotọ &c.,
JAMES WHITE,
Sajin awọn Ọlọpa.

Freetown,
21st December, 1922.

Awọn iru nkan bawọnyi ni awọn ohun abami ti ima farahan ni igba iku awọn olokiki enia.

Mo ro pe, Shakespeare gba iru ohun bayi gbọ, nitori o sọ bayi nibikan ninu awọn iwe ti o kọ pe:—

"Nigbati awọn alagba ba ku, a ki ri irawọ oniru kan, Şugbọn nigbati awọn ọmọ alade ba ku, oju ọrun papa a tan imọlẹ".

## ẸKỌ FUN AWỌN TI KO TI KU.

Ko si iyemeji rara pe igbe aiye ọrẹ wa ko le şe alaima jẹ onjẹ ironu fun awa ti o şi wa lori ilẹ, nigbati a ba nwo bi o ti lo akokọ ti a yọda tun u laiye yi. Ede awa papa ni ilẹ wa tubọ kinrin ọrọ wa lẹhin ninu orin wa pe:—

Oku y'oku k'a mi sun
Awa 'ra wa la mi sun.
Awa 'ra wa la mi sun (2)
Oku y'o ku k'a mi sun, oşe,
Awa 'ra wa la mi sun ! ! !

Ẹnyin ara ilu mi, ẹ jẹki a lo akoko wa laiye tobẹ, lẹhin ti a ba ti şiro işẹ iriju wa tan, ki iran wa ati awọn iran ti a ko ti bi le dide ki nwọn si pe wa ni alabukunfun, gẹgẹbi o ti ri nisisiyi fun ọrẹ wa ologbe—Dada Adeşigbin.

Milton sọ bayi nipa "Igbe aiye Enia" pe:—

Maşe fẹran ara rẹ, maşe korira;
Şugbọn igbe aiye rẹ, lo o daradara
O kuru ni, o gun ni, fi eyini le Ọlọrun lọwọ.

Ẹwẹ, Seneca, ọlọgbọn ara ilu Grisi sọ wipe:—

"Işẹ ni a fi wọn igbe aiye enia, ki işe akoko ti o gbe laiye, enia le di arugbo ni ọgbọn ọdun, ki o şi jẹ ọmọde li ọgọrin ọdun.

Ekini wa laye lẹhin ti o ku tan,
Ekeji ti ku, ki o to ku".

"Iku ko si.
Eyiti o dabi iku ni ipapoda;
Aiye iku yi
Ọna ajo şa lo jẹ si ilu aiku (ilẹ Elisi)
Ẹnu bode eyiti a npe ni Iku".—Longfellow.

"Iku ni so ni pọ mọ awọn ti o ti ku
Bi ẹnipe a tun bi wa lati ri awọn bi Plato ati
awọn awọn bi Kesari,
Lati di ẹni ola titi aiye.
Adun ni, ayọ ni, nigbana lati ku".—Young.

"On ko ku
Ẹniti ọkan rẹ
Ngbe tire ga soke
Lati wa lọkan awọn ti a fi silẹ lẹhin
Ki şe lati ku".—Shakespeare.

"Mo gbọ ohun kan lati ọrun wa nwi fun mi pe,
Kọwe rẹ lati isisiyi lọ
Ibukun ni fun awọn oku ti o ku ninu Oluwa.
Nwọn simi kuro ninu lala wọn.
Işẹ wọn si ntọ wọn lẹhin".—Ifihan ti Jahannu.

*Ma sinmi l'alafia.*

ORI II.

## IWA—AGBARA TI ẸKỌ ILE N..

(*Translated from "Character by Dr. Smiles"*)

APA KEWA.

Eyiti ẹniti o kọ iwe itan Cromwell nipa ti baba rẹ ko to nkan, ti iwa iya r.. o sọ ju, o ni obinrin bi ọkọnrin .. "obinrin ti o ni ọgbọn ati ẹbun bi a ti.. ọwọ ẹni tun ti ara ẹni şe nigbati ko ba .. oluranlọwọ; ẹniti o mura tan lati fi ara .. ayida-ki-ayida ti o le de, bi o ti wu ki .. buru to, ẹniti, bi iwa jẹjẹ ati suru rẹ ti .. to, bẹni ọkan nini ati itara rẹ si to; ẹni.. nipa ogun oju rẹ tabi işẹ ọwọ rẹ, o sin ọm.. marun ni iyawo—dukia ti o fi sin wọn lọ.. ile ọkọ tabi ti o fi da wọn ni okowo to gà.. ni ti ọmọluwabi, afi ti ẹni i o ni owo ju t.. lọ ni a ko mọ; ẹniti o jẹ pe fuja kan ti o.. ni ododo şişe, ọkan ti o ni si ni ti ilẹ.. ẹniti o jẹ pe ọla ko kun loju, iwa aini akẹ.. tabi ki a ma şe pẹpẹfuru ti ima hu, eyiti .. mu gbogbo enia ma gba fun nigbati o w.. ile ipọn-ọti ni Huntingdon, ko fi iwa .. silẹ ani nigbati o di gbajumọ—larin awu.. awọn alaiye ninu afin Whitehall ti o n.. arinrin; ani ẹniti o jẹ pe larin gbogbo ọl.. rẹ ko du nkan meji afi ki nkan ma şe ọm.. rẹ ti o wa ninu ipo giga, ipo ẹlẹgẹ."

A ti sọ nipa ti iya Napolen Buonaparte gẹgẹbi o ti jẹ obinrin ti o ni iwa. Bakanna ni ti iya Duke of Wallington, ẹniti ọmọ rẹ jọ tojutoju, taratara ati tiwatiwa; baba rẹ ẹwẹ, si jẹ ẹniti gbogbo ilu mọ ni alarofọ— ọkọwe orin ati ọkọrin. Şugbọn ohun ti o ya ni lẹnu ni pe iya Wellington ro pe ọdẹ kan ni ọmọ on; a ko mọ bi o ti ri, iya rẹ ko fẹran rẹ bi o ti fẹran awọn ọmọ rẹ iyoku, afi nigbati o di agba tan ti o wa şe awọn ohun ribiribi ni ilu, eyiti o mu iya rẹ wa mọ iyi ọmọ rẹ.

Awọn ọmọ Napier şe ori rere, ko si bi o ti ri ni awọn obi wọn mejeji, papa ni ti iya wọn, Lady Sarah Lennox, ẹniti o ti k.. wọn lati kekere lati ma ro ero rere, lati ma gba fun ohun gbogbo ti enia ba şe, ti o jẹ rere ati lati ni ọkan akọni, awọn iwa ti o d..

ara fun wọn, ti o si jẹ iranlọwọ fun wọn lọna gbogbo titi ọjọ iku wọn.

Ninu awọn Oṣe-ilu, awọn Amofin, ati awọn Ojiṣẹ-Ọlọrun, a ri i pe a tenu mọ ti iya awọn Lord Chancellor:—Bacon, Erskine ati Brougham—awọn obinrin ti ọgbọn wọn ko kere, papa ti iya ekini (Bacon), ẹniti iwe mimọ rẹ ko lẹgbẹ; bẹ si ni ti awọn iya Canning, Curran ati ti President Adams—ti awọn iya Herbert, Paley ati iya Wesley pẹlu.

Nigbati Lord Brougham ba nsọrọ iya rẹ agba, arabinrin (*sister*) Professor Robertson, o ni on ni ẹni pataki ti o kọ on bi a ti tọ pinpin ati bi a ti wadi nkan, on ni o si kọko kọ ọ ni suru ati iforiti ti en a fi ikọ gbogbo ọgbọn lọnakọna, iwa ti a mọ mọ ọ ti o si di ara fun titi o fi tẹrigbaṣọ.

Iya Canning ara Ireland ni iṣe, titi ọmọ rẹ—ẹniti o jẹ oni-mimọ fi ku ni o fi ni ifẹ ati ọwọ nlanla fun iya rẹ Obinrin ti o mọ wabiwọsi iwe ni Opitan Canning sọ pe, "Ni gasikia, bi a ko ba ti gba ọna miran mọ irufẹ enia ti iya rẹ jẹ ni, ti a ba wa nwo iru ifẹ ijinlẹ ati ọwọ ti o ni fũn, a ko le ṣai ni ero pe, ẹniti a ni iru ifẹ ti ki iti bayi fun, enia pataki ni. Awọn ẹgbẹ ati ọgba rẹ mọ pe ẹniti o ni mimọ gan ni. Ọrọ sisọ da si i lẹnu, iṣe-ẹnu sọrọ rẹ ki iṣe ti alafarawe, o mọ ile ọrọ, ki iṣe ajawiyin. Iwa itara tabi ayan ti o ni, loju awọn ẹniti ko ba lo mọ daradara, fẹrẹ jọ ti ẹlẹgan tabi ẹniti ori rẹ ko pe."

Tifẹ-tifẹ ni Curran fi sọrọ iya rẹ gẹgẹbi obinrin ti o gbọn pupọ, ati pe imọran rẹ, iwa rere ti o duro dede, pẹlu ẹkọ ki a ma lepa ohun rere, awọn yiti o ṣe lala lati fi kọ awọn ọmọ rẹ, ọpẹlọpẹ iwọnyi lara on (Curran) ni on fi le de aye kan l'aiye.

O ma nsọ pe, "Iba ogun ti mo le taka pe mo jẹ lọwọ baba mi ko ju eyi lọ, pe mo fi aini-ẹwa oju jọ ọ; bi awọn araiye ba si gba pe emi ni ohun miran, eyiti o ju ẹwa oju lọ, tabi ti ohun ini aiye, a jẹ pe iya mi ẹniti o ṣe ọwọn fun mi ju baba mi lọ, ni o fun ọmọ rẹ ni diẹ ninu iṣura ọgbọn ti o ni."

*Koi ti pari.*

*Translated By*

ADEYINKA AJAGBE-ỌSA

INA WỌ'LE OKUNKUN PARADA.



Atupa ti a npe ni "Oṣupa mi" jẹ oju-lowo ati papin atupa hanun ti o si yẹ ilekile, papa ile awọn gbajumọ olowo, a ko le ṣẹṣọ ma sọ ti awọn "Dẹngẹ". Agbara rẹ pẹlu agbara atanpọ ọdunrun abẹla, dede ni, bi ọsan si ni titan rẹ ri ninu ile. Agba ti koi ti lowo gbigba Atupa Ṣango sile ki o ma jafara lati ra atupa meremere yi ti o na electric jẹ.

Oriṣi meji lo wa fun tita: **ti oni-fadaka** ati ti onidẹ

Ẹ lọ yan ti nyin ni Ṣabu Oyinbo KESSLER ni No. 7, Labinjọ Lane.

Ẹnyin ara-oke ati ilu miran, ẹ maṣe gbẹhin ki ẹ to ranṣẹ ti nyin, ki ẹ ma ba j'oku ologbo.

**EKO AKETE**

EKO, SATURDAY, FEBRUARY 11, 1928.

## EKO R'OGUN, KO R ỌKỌNRIN, GÃSA, IGIDA!

Ẹnikẹni ti o ba fi lakaye ka Ọmọnkele ti o kun Iwe-irohin Ọsọsẹ Ijọba ti ọjọ keji ogu yi *( Supplement to the Nigeria Gazette of 2/2/28 )* yio ri aba ofin titun kan ti a npe ni *The Town Planning Ordinance,* eyini ni Ofin Tito Ilu Eko ti Ijọba npete lati sọ di ofin; ọrọ pẹteri ninu Aba-ofin na, diẹ ninu awọn ohun ti o ṣe pataki ti a kiyesi ni (1) Ijọba yio yan awọn Igbimọ ti yio ma bojuto mimu ofin na ṣẹ kete ti siṣo rẹ ba ti di criṣa, (2) Ilekile ti Ijọba ti bi awọn Igbimọ ba ri pe o dina, Ijọba yio ke si awọn onile na pe ki nwọn wo, awọn yio si san owo ti ile na ba to loju wọn fun awọn onile na; ti nwọn ba si kọ lati wo ile na, awọn onile na yio ni lati ṣe kokari ati ko kikọ wọn siwe ṣọwọ si awọn Igbimọ ti Ijọba ti yan yi, ti Igbimọ na ba si dã ro, ti nwọn ba ni lotọ ni tẹtẹ jẹ ile na ni wiwo, ti eyi ko ba si tẹ awọn onile na lọrun, nwọn le kọwe ṣọwọ si Gomina Agba ni Igbimọ, eyiti Gomina ba si sọ ni abẹ ge, ki a ya bara ki a p'owe kan, tani eṣinṣin iba gbe bikoṣe ologodo— ki o ma ye ọ, lẹhin gbogbo wahala ati inawo ti gb gbo hilabilo yi yio mu wa ti awọn onilẹ na ba si kọ lati wo gẹgẹbi Ijọba ti fi oke le, fun oṣu kan gbako, njẹ Ijọba yio wa t'ẹsẹ bọ̃ lati ba oluwarẹ wo, nwọn yio si gba gbogbo owo ti nwọn ba na lati wo ile yi lọwọ oluwarẹ mwọn yio b'omi ṣãn lọwọ b' o fẹ b' o kọ; (3) Ẹwẹ, ti Ijọba tabi awọn Igbimọ yi ba ri pe kikọ ile kan ko dara loju wọn, nwọn yio ke si onile na pe ki o tun kọ ni kikọ ti yio tẹ wọn lọrun, ti onile ba si sọ pe ọwọ on mẹwẹwa re, ko si owo kan lọwọ on fun iṣẹ apapandodo na: Ijọba yio sọ pe awọn yio ya ni owo ti ele rẹ ko ni tã lara, oluwarẹ si ni lati fi ile na mọgeji fun Ijọba titi yio fi ri owo ti nwọn ba ya na san pada ati ele. Adugbo-kadugbo ti Ijọba ba ṣe gbogbo anfani wiwa jẹlẹnkẹ fun awọn enia si, yio ni lati ma san owo ti nwọn npe ni *Rate dues* s'apo Munisiba. Owo titun yi ko ma papọ mọ owo omi ti oluwarẹ nsan o tabi owo sisan miran pẹpẹpẹ tabi owo asingba *( Income Tax )* ti a o bu ni sisan fun oluwarẹ.

Iba diẹ ti a ṣi ṣa ninu aba-ofin Tito Ilu Eko *( The Lagos Town Planning Ordinance )* ti a toka si leyi, a ko si le ṣe a'ai sọ diẹ na fun ẹnyin ilu gbo; bi inira miran tun mbọ ti aba yi ba di ofin bi ko bọ, a fi didaro rẹ le ẹnyin agbalagba lọwọ: ṣugbọn ọkan ni, a ko ni ye sọ eyini ni pe bi orisiriṣi koba-kungbe ofin ti nkolu ara wọn larin Eko lode oni, Baba nikan ni yio mọ ohun ti o ma gbẹhin gbogbo rẹ: nitotọ Ijọba sọ pe ofin Ilu Eko tito wa fun atunṣe Eko ti o fun gadigadi nisisiyi, a tanma pe ọna ti Ijọba ngba lati ṣe evi nipa aba ofin ti nwọn tẹ na ki yio jẹ ti Ãya ti o ni on tun oju ọmọ on ṣe, ti o si t'igi bọ; ki a ya bara si ọrọ miran; ẹ wo awọka ti ogoro awọn ọmọ-ile'we ti ofin d'ọmọloro ti Ijọba npe ni Ofin Ẹkọ kọ lati gba si Ṣukuru nwọ kakiri ilu nisisiyi, ṣe ohun ti o dara, ohun ti o yẹ ilu leyi; a gbọ ti awọn ọmọ olowo; ṣugbọn olowo nikan lo ni ilu bi? A ṣebi ilu ni Are ngbe? Ṣiọ! ọgẹdẹ nbajẹ, a lo npọn, wundia nfọko, a lo nṣoge! e ma d'ọwọ nyin o, ẹnyin agbagba Eko; njẹ talo le no'ka iye awọn Enia Dudu ti yio ku l'Eko yi lẹhin ọdun pupọ bi gbogbo nkan ti nlọ si yi!

Kẹ ẹkẹrẹ ajeji nd'onilẹ,
Ajinifẹ nd'ọkọ ẹni.

---

## MO NGBA, REVEREND GRIFFIN, MO NGBADUN RẸ!

[ WOSIKA LATI ỌWỌ ATARI JANAKU ]

---

Mo bẹrẹ f'oji

Aṣa Ẹgba mọ ni mọ ni, nwọn ni e ni-ba ṣe rere, ki a lu u ni ọgọ ẹnu, O ṣe e pọ. Irufẹ ọgọ ẹnu bayi ni a ro pe o yẹ ki a fi lu Reverend Superintendent Griffin, Olori Alufa tabi "Bisọpu" awọn Ijọ Wesleyan l'Eko ati jakejado Nigeria, pe

o ṣe pọ fun wahala nla to nṣe ni lọlọyi nipasẹ iwe ol'obinrin kan ti a gbọ pe o nfẹ ki ọpọlọpọ ninu awọn mẹmba Ṣọṣi rẹ fi ọwọ si lati duro ti obinrin alarede kanṣoṣo ti nwọn ti gbe, tabi lati jẹjẹ pe, bi baba npa wọn pẹlẹbẹ, ti iya nfi nwọn rọ kọbọ, idi ọrọ olọrọ ni obi nku si, ọrun alarede wọn ni yio ku si.

A le wipe eyi ko dara, a le wipe Reverend Griffin ko fẹran awọn mẹmba rẹ, Agbẹdọ. O fẹran wọn pupọ, o fẹrẹn wọn ju oju lọ, iba ma ṣe pe o fẹran wọn pupọ nkọ, o le ṣai ba wọn gbero bi eyi ti ko riṣẹ ṣe ninu wọn ti ṣe le ri iṣẹ ṣe, bi awọn mẹmba rẹ pẹlu gbogbo Ilu ti ṣe le bọ lọwọ àjágà ofin Esu adaiko (*Income tax*) ti Ijọba fẹ gba lọwọ wa, nipa bi ba wa bẹ Ijọba; ani, bi Reverend Griffin ko ba fẹran awọn Ijọ rẹ pupọ, o le fi gbogbo nkan ba nwọnyi silẹ laiṣe, ki o ṣe pe ọrọ arede ṣa lo dun u ju, papa lẹhin igbati on papa ti ra tan, ti o ti ta tan larin wa, ti o si nmura lati ba ẹsẹ rẹ sọrọ kuro ni ilu wa.

Nigbati awọn Alufa Ṣọṣi miran ba nfi ọrọ tamutamu silẹ, ti nwọn ba njẹ ijanu lori ọrọ arede bayi, bi ẹnipe nibẹ nikan ni igbala ẹmi awọn Onigbagbọ wà; ibere ti o ma nsaba wa si ọkan wa ni pe Ẹmi Ọlọrun lo ha nda'ri won ni, tabi ẹmi ẹṣu?

Ọpọlọpọ Ṣọṣi lo dabi ẹnipe ko bikita bi ẹnikẹni ninu mẹmba Ijọ rẹ jẹ ole, tabi apania, eke tabi anikanjopọn, ti o ba sa ti jẹ alarede, o ti buṣe; kọkọrọ Ijọba Ọrun ti wa ni ọwọ rẹ ni yẹn. Irọ rọ. O di ẹjọ idajọ. Ki a ma ṣẹṣẹ sọ ti mẹmba miran papa to gbe arede ti ko si tọju iwa rẹ ni nwọn ma fi tẹlẹ ina Ọrun Apadi, tabi Kılapo?

Arede, arede; Kilo tilẹ nya apari Reverend Griffin l'ori to fẹ mõkun l'odo? Ṣọṣi ẹlẹja ko ha ko l'ogbọn to ni? Arede ti nwon ngbe ni ilu Oyinbo ilu rẹ, ire kilo ṣe nwọn? Omi igbin ko tu igbin, ẹ ni he ni on he ẹrọ; Iboya kẹ, bi ọpọlọpọ awọn ara Ilu rẹ ti ngbe iyawo loni, ti nwọn nfun wọn ni iwe ikọsilẹ lọla, lo ro pe nwọn fi nṣe nkan gunmọ loju wa

Nigbakigba ti ọrọ arede ba de'lẹ, awa le sọ gbangba pe, ko si agabagebe enia, tabi jodi-jẹsọ enia to ju awọn Alufa Ṣọṣi lọ, nwọn igbati nwọn ba ti nle gbe obinrin ti a ti kọ silẹ ni iyawo (*a Divorced woman*) fun ọkonrin miran, ohun ti o lodi patapata si ofin arede to wa ninu iwe ti nwọn.

Nigbati nwọn ba ngbe iyawo fun t'ọkọ t'aya ni Ṣọṣi, pupọ ninu wọn a ma lagun bọyọ bi aruwọ, nwọn a ma wipe, "ẹnikẹni ko gbọdọ tu awọn ẹni meji yi ti Ọlọrun ti so pọ ka" *Wkomsoever God joineth together, let no man putteh asander.* Lẹhin ti nwọn ba ti fi ẹnu wọn ṣe ètè l'ọṣọ bayi tan, oju wọn kanna yi ni t'ọkọ t'aya ṣe ma ru ara wọn lọ si Kotu ti Onidajọ mã tu wọn ka; wọn ko ni wukọ, wọn ko ni ha kẹlẹbẹ: kaka bẹ, bi ẹnikẹni ninu awọn meji to ti ja ajatuka ti agbãnrin bayi ba tun fẹ gbe ẹlomiran ni iyawo lẹhinna, ti nwọn ba ti ri ṣile mẹwa abọ, tabi pọnwun kan ṣile kan gba, o di ki nwọn tun lọ ko agbada wọ, ki nwọn lọ ṣe iyawo na fun wọn pẹlu awawi ti nwọn nwi pe "Ẹnikẹni ti Ọlọrun ba ti so pọ, ẹlomiran ko gbọdọ tu wọn ka mọ; bi ẹnipe ni orukọ Ọlọrun kanna ti nwọn ti fi so Mary pọ mọ John, kọ ni nwọn tun fi so Mary kanna pọ mọ William lẹkeji. Aṣa yi ko ha dabi ẹnipe Ṣọṣi nmọ ọkọ ọmọ tan, o tun nmọ ale rẹ pẹlu?

Arede ko nṣe ofin ẹsin, àṣà ilu Oyinbo ni. Ko dabi iyigi ti awọn Musulumi nso, nitoripe igbeyawo ni ọna ẹsin patapata ni eyini—"bãbu kọlọkọlọ. Alufa ti o so yigi le tu lẹhinna bi tulasi ba de; Musulumi ko le nde Kotu ki o to tu yigi, nitoripe Kotu kọ lo so fun wọn Ṣugbọn iwọ Kiriyo nkọ o, ọbigilawọ, tirẹ ko di ọran Lọya, ko di ọran Kotu, ko di ọran anọtunnọ owo; iranlọwọ elo ni Ṣọṣi nṣe fun ọ, tabi iru iranlọwọ wo ni nwọn tilẹ le ṣe fun ọ, nigbati arede ba di ẹti si ẹ l'ọrun?

Gẹgẹ bi a ti wi ṣiwaju, a ko wipe arede ko dara, ṣugbọn ohun ti a fẹ lati la ni alaye nibẹ nipe, Jesu sọ fun wa pe, a ki ngbe iyawo l'ọrun, ohun aiye ni; a si pe Alufa ki Alufa ni ija ti o ba le sọ fun wa, inu iwe ti o ba wa ninu Bibeli wọn pe o tọ suna lati gbe ẹniti a ti kọ silẹ ni iyawo (eni); eji, pe bi Ọlọrun ba ti so t'ọkọ t'aya pọ tan ni Ṣọṣi, Onidajọ aiye le tu wọn ka; ati eniruru ofin miran ti Ijọba so mọ igbeyawo l'ẹsẹ. Ani, Alufa ti o ba le tọka si ibi ti iru ofin bẹ wa ni Bibeli, ao fun Alufa na ni apoti Ọti *Whisky* kan, Ṣago ẹmu meji.

Ki a tun pada sẹhin? gẹgẹ bi ofin arede ti wa loni pẹlu gbogbo inira ati aidara rẹ fun ọpọlọpọ Enia Dudu apa ihahin ati pupọ ninu Oyinbo papa, ko nṣe ẹjọ awọn Alufa Ṣọṣi; ẹjọ Ijọba ni. Ikate f'ori gbu si lasan ni ti nwọn, iku to npẹja wa nisalẹ omi Ṣugbọn ibi ti ẹbi awọn Enia Dudu to gba iṣẹ Afa Ṣọṣi wa ni idakẹ wọn, jẹjẹ korodo wọn, iberu wọn, ati ojo wọn, lati sọ otitọ tun Biṣọpu Oyinbo Oga wọn, tabi *Superintendent* Oyinbo Olori Ijọ wọn pe, aṣà arede olobinrin kan, àṣà Oyinbo ni, o lodi si aṣa ilẹ wa; ati pe, ọpọlọpọ awa Enia Dudu to ti gbe arede, arumọjẹ ni; Kareta ni a ṣe. "Awa ko le joko jẹ, awa ko le joko jẹ, ẹsẹ wa nta felefele, awa ko le joko jẹ." (Ibà Orlando Furioso).

O san pupọ loju wa ki nwọn sọ otitọ, ju ki nwọn fi agabagebe, nitori ati jẹun, pa otitọ mọ'lẹ Lọ. Biṣọpu ha le tori otitọ yọ gbogbo wọn nişẹ tan? Agbẹdọ; bi o ba si tori rẹ yọ nwọn nişẹ, eyini ha wipe ebi ni yio pa nwọn ku? Agbẹdọ.

Ẹ ranti itanna to wa ni'gbẹ bo ti ndagba, wọn ko nṣiṣẹ, bẹni wọn ki nran'wu; sibẹ, a ko ṣe Solomon papa l'ọṣọ ninu Ogo rẹ, to ọkan ninu awọn itanna nwọnyi.

Ibaşe pe pupọ ninu awọn Alufa Şọşi ti nso iru otitọ bayi, ti aşọ loni; gbogbo wọn ni iba si ni ifẹ ati irẹpọ si ara wọn, dipo "egbogi agbelepọta" ti t'ọtun t'osi nsa. A ha fi Kristi kọ nyin bẹ, ẹnyin Onikekere igbagbọ?

Inu wa dun pupọ pe Revd Suprintendent Griffin gbọ Yoruba daradara, eyi ti yio jẹ ki o ka wosika wa yi fun 'ra rẹ, laisi iranlọwọ Ogbufọ.

Oyinbo miran le wipe ailera ni ko jẹ ki Enia Dudu ni itẹlọrun pẹlu obinrin kan, o si le sọ oniruru isọkusọ miran pẹlu. Şugbọn gẹgẹ bi ọkan ninu awọn orin aladun Serafu, "B'aiye nşata, pẹlu eşu, eke ni nwọn, nwọn nşe lasan."

Ailera wa ha to ti pupọ ninu awọn Oyinbo ara ilu Revd Griffin papa yala, nilẹ yi tabi ni ilu wọn nibiti nwọn ntẹ obinrin kanşoşo? Iba ma si işekuşe, ailera, ati ifẹkufẹ Oyinbo, nwọn a ri Enia Dudu ni ilu wọn, ti nwọn ko mọ ile tabi ọna rẹ, iya tabi baba rẹ. Nwọn a re mọ bi pakute pe ki o gbe wọn ni iyawo; asinwa, asinbọ, nigbati ẹlomiran ninu wọn ba de ilẹ yi tan, o di ki nwọn ma tun re mọ awọn ọmọ "oju ẹọta" Oyinbo ara ilu wọn nilẹ yi ẹniti wọn ko mọ ri rara ni ilu wọn lọhun, ilu ọdaju on oşi, nibiti ebi npa nwọn ku lojojumọ, ti ẹlomiran ninu wọn si nnu bata ẹsẹ Enia Dudu ki o to ri kọbọ kan gba fi jẹun.

Ni ilu *Nigeria* ti wa yi nkọ, a ha le ka iye Mulato ọmọ Oyinbo to wa nibe, lai ka Oyinbo miran ni Eko kanna yi to nle nu kiri bi obukọ lẹhin awọn Kuntakuna; ani, lai ka awọn ti kọkọrọ ori wọn nsọnu gbárà ti nwón ba ti fi oju ri ọdọmọbinrin Eko to gb'afe die, to wa ra oja ni Şabu wọn. Nwọn fẹrẹ le ko gbogbo oja olọja, oja ẹlẹba wọn, to wa nibẹ fun obinrin lọfẹ.

O yẹ ki Revd. Griffin ati awọn Oyinbo oniwasu ẹgbẹ rẹ kọkọ yọ iti igi ẹşẹ aimọ to wa loju awọn Oyinbo ara ilu wọn lọhun ati ni ilẹ yi kuro, ki nwọn to daba lati yọ erun igi lasan ti nwọn ni o wa loju wa kuro. Ile ni a ti nko ẹsọ r'ode.

Anu şe wa pupọ lati ri pe ọrọ olobinrin kan yi ni Revd. Griffin fẹ fi pari işẹ nlanla, işẹ ribiribi ti o şe ni Nigeria larin wa, fun eyiti a dupẹ lọwọ rẹ gidigidi; şugbọn gẹgẹbi *Eko Akete* ọsẹ to kọja ti wi, ko yẹ ki Oyinbo şu s'aga, nigbati o ba fẹ lọ. Ki a tilẹ wipe nwọn fi ọwọ si iwe fun u, iyẹn ha le pa aşẹ ilẹ wa rẹ, iyẹn ha wipe lẹhin ti ọkọnrin kọkan bi ti gbe obinrin kọkan ni iyawo tan, ki awọn obinrin to şeku sile gbe igba şina le'ri, gẹgẹbi nwọn ti nşe ni ilu Oyinbo? Agbedọ, Ọlọrun ma jẹ. O di ori igba, o di ori awo, o d'ori agb'ẹbọ ma ru.

A ko le wipe ki ẹniti o fẹ, maşe gbe iyawo; iyawo dara. Bi awa papa ba si şe obinrin, bi a hu ewu, irun funfuu, sori bayi, arede ni ao ma duro de, nitori lati r'aye pa işẹ nile ọkọ, ati nitor ati nikan le jogun ile ati ọna ọkọ, lai pin ẹnikẹni nibẹ.

Şugbọn bi arede ti wa wa to ni, a ko le şai ... pe o lodi si aşa ilẹ wa, ati pe aşa ilẹ tiwa ... pupọ ju arede Oyinbo lọ. Lai ba ẹnikẹni ninu ... pupọ ninu awọn ẹni nla wa ni arede ko gbe; pupọ ninu wọn ni arede obinrin kanşoşo ti jẹ ki o ... akurun lai f'ọmọ silẹ s'aiye; boya ẹsẹ ẹlomiran ninu wọn si wa ni bebe ọrun nisisiyi ti arede ko ... ki o r'aye parọ ara rẹ silẹ

A ko nri agan ọkọnrin, bi ti alare le ... mira kọ. Ọlọrun ko şọ wa nibẹ. Şọşi ko se to, o ... ki nwọn s'ofin ki gbogbo ẹniti ko nşe ọmọ alare ... kuro ni Şọşi, nigbana ni ao to mọ iye Afa papa ... le duro, lai ka mẹmba!

Revd. Supt. Griffin, ẹsọ ko to ẹ.

Emi ni ti nyin nitotọ,
ATARI AJANAKU.

## OLUSAKIN'S COLUMN.

### M.P.'s visit to Lagos.

Three members of Parliament left Liverpool for Lagos last week in the Elder Dempter liner "*Adda*." They are Major Walter E. Elliot, member for the Kelvingrove Division of Glasgow, Under-Secretary for Scotland; Mr. G. M Garro-Jones, Liberal representative of South Hackney, and Mr. William Lunn, Labour Member for Rothwell, Glasgow.

They are not going as a Government Commission but as the outcome of a suggestion at the Colonial Office conference in the summer by Sir Graeme Thomson, Governor of Nigeria, who said he would be pleased to see any members of Parliament who called to pay him a visit to Nigeria. The party, who are interested in the Empire Parliamentary Association, are going out under arrangements made by the Colonial Office. They will leave Lagos on February 10, for Plymouth.—*The Times Weekly Edition 29/12/27*.

### The arrival of Parliamentary Delegation.

We welcome the members of Parliament, Major Walter Elliot, and Mr. Garro-Jones, who returned to Lagos on Monday the 6th instant, after an extension tour of the country for about a month. And Mr. William Lunn, M.P., had left them at Ibadan when going from Lagos, and he had since gone back to England through indisposition.

### Candid Communications.

OUTSPOKEN MESSAGES TO CELEBRITIES NOTORITIES AND OCCASIONALLY NONENTITIES.

To the Rev. Herbert Dunnico, M.P.,
King's Buildings, Dean Stanley Street, S.W.

Dear Sir,—You tell us that the opponents of the Prayer Book measure spent £100,000 in order to defend it, and you believe that the money could have been used to better purpose in the case of the million miners and their dependents who are on the verge of starvation. I like you believe in a religion which ministers unto the needy, even as the great Founder of Christianity taught us to do.

To the Lord Archbishop of York,

Bishopthorpe Palace, York.

Your Grace,—Your reminder on New Year's night of the duty of peace within the Church was a welcome "come-back" to Christianity. Self-restraint is a duty no less glorious than self-sacrifice. If there is not room in the Church for all movements and schools of thought, then the Church has outlined her usefulness. In pleading for peace, within and without, you at least have grasped the meaning of the Gospel.—*John Bull*, 14/1/28.

### Arrival.

Mr. E. A. Oluyẹle Bright of the Nigerian Railway' Ebute Meta, who has been touring Kano, Zaria, Ibadan, Ede, Oshogbo and Ile Ifẹ on leave as from the 9th January last, has now returned to town on Thursday morning the 9th instant, 1928.E kabọ.

### The resumption of Mr. Owolabi Ebinisi to his Duties.

Mr. Owolabi Ebinisi, (alias Petson) Assistant Accountant, Nigerian Railway Traffic Audit, Ebute Meta, who has been on three months' vacation leave, since 1st November, 1927, has resumed his duties from the 1st February, 1928.

### Birth.

Madam Sarah Arọbalade, wife of Mr. P. D. George, 10, Upper Offin Road, Lagos, was delivered of a son on Sunday, the 5th February, 1928. It is reported that both mother and child are doing well. Congratulation.

### Scene in St. Paul's

MAN EJECTED BY VERGERS AFTER MAKING PROTEST DURING SERVICE.

When the Rev. T. Wellard entered the pulpit at St. Paul's Cathedral yesterday morning, the congregation was startled to hear a voice raised in protest.

The man who protested was seated behind a stone pillar, and spoke for some moments before being located.

Part of the protest which the congregation heard was :—"In the name of the Father, and the Son, and of the people of England, I protest against the ministers of this Church continuing to act as Christian Ministers, on the grounds that they are the greatest accessories in the most hellish wrongs in defiance of the laws of both God and man upon the people and the poor by our own political and local ministers, Judges, Magistrates, law officers and chiefs of police."

As the man refused to leave, he was ejected by three vergers. He refused to give his name or address—*The Daily Mirror*, 9/1/28.

### Resumption of Duty.

Mr. L. A. Ojo, 2nd Class Binder, Railway Press, Ebute Mẹta who has been on a month's leave as from 3rd January, 1928, and resumed his duties from the 3rd February, 1928.

### Death of Mr. James O. Hotonu.

The death took place at 31, Offin Road, Lagos, on Friday afternoon the 27th January, 1928, at about 3.30 p.m.

His mortal remains were removed to the King's Church, Enu Owa the following morning at 9 a.m., before a large concourse of people. The Archdeacon of Lagos, Venerable T. A. J. Ogunbiyi and Rev. W. O. Aiyedun officiated. And thence to Ikoyi Cemetery for interment.

**Mr. Ọladipọ Hotonu was an exemplary Christian, a member of Parochial Committee, and was a pillar of Enu Ọwa Church.**

**Mr. Hotonu had been in indifferent health.**

**To Mr. Ebeneaer Hotonu, Mr. E. Adebọ Allen, Mr. J. A. Aromirẹ and all the bereaved families of the deceased, our sincere condolence. Aged 54. *R.I.P.***

**OLUṢAKIN.**

## IGBIMỌ-AṢOFIN

LATI ỌWỌ KEKERE-AWO.

Si Oniwe-irohin "Eko Akete,"

**Mo bẹrẹ foji o,**

Gẹgẹbi a ti gbọ si, Igbimọ-Aṣofin ti ilu (*Legislative Council*) ku ọjọ mẹjọ loni eyiyi ni ọjọ 18 oṣu yi

Lẹhin Igbimọ ti Ijọba tiṣe lọjọ 23 oṣu August ọdun to kọja (1927) ti nwọn si fi ọjọ meji pari rẹ, Ijọba koi ti iṣe Igbimọ k'Igbimọ mọ, bikoṣe eyiti nwọn yio tun ṣe ni Satide to mbọ yi gẹgẹbi a ti gbọ si.

Igbimọ na li yio si jẹ ekini ti nwọn yio ṣe lati igbati a ti bọ sinu ọdun (1928) Ọdun titun.

Ninu Igbimọ ti a sọ wipe nwọn ṣe gbẹhin, li a ri wipe nwọn gbe ọran ofin owo-ajulọ (*Income-Tax*) siwaju Igbimọ eyiti oyinbo J. C Howard, ẹniti o mbẹ ni igbakeji Agbẹjọro-Ọba fun oyinbo Kingdon, ka iwe ofin gẹgẹbi ṣawura ti Igbimọ fifun wọn lati ṣe nipasẹ ọran ofin owo-ori, lẹhin igbati awọn enia wa ati awọn oyinbo ti fi aidara ti o mbẹ ninu owo-ori sisan han ni Igbimọ ti ọjọ karun oṣu April 1927, ti Igbimọ si yan awọn enia mẹsan, oyinbo meje, enia dudu meji lati ro ọna wo lo tun dara, ti Ijọba tun le yi owo-ori gbigba na si, lẹhin igbati Ọlọla Gomina Thomson papa ti ri wipe iyapa ẹnu mbẹ lori gbigba owo ori ni Igbimọ ti ọjọ 5 April 1927.

Oyinbo J. C. Howard, igbakeji oyinbo Kingdon Agbẹjọro-Ọba papa, o mbẹ lara awọn ẹni mẹsan ti Igbimọ yan lati ṣe ṣawura titun miran fun owo-ori.

Gẹgẹbi o ti jẹ wipe oyinbo Howard yi lo mbẹ ni Agbẹjọro-Ọba, o fihan Igbimọ gẹgẹbi nwọn ti ṣe ṣawura ọna ti Ijọba yio tun mu owo-ori gba si, o si ka gbogbo iwe ọran ofin titun na si iwaju Igbimọ, eyiti ofin na si di kikọja, gbogbo wa li a ti gbọ ti a si ti mo eyi, nipa rẹ, ko tun jẹ ohun iwuri pataki fun wa mọ lati tun ma patoto ẹnu bi ẹiyẹ ẹga.

Ṣugbọn eyiti a ri wipe o tọ o yẹ lati ṣe ni iṣẹ lori rẹ ni wipe, ti nwọn ba ṣe Igbimọ ti o mbọ yi tan, ao mura lati rohin ọrọ olukuluku awọn Ọlọla na ni kikun ni Igbimọ ti ọjọ 23—24 oṣu August 1927, fun nyin.

Nitoripe lati igbati a ti nrohin ohun ti nwon ṣe ni Igbimọ lọjọ na, a koi ti fi yẹkini iṣẹ ti Olukuluku ṣe ni Igbimọ han ki ofin na to di ohun ti gbogbo wa ngbọ wipe, nwọn pari rẹ pe a ni lati san owo Ajulọ ni ilẹ yi, ki awọn Igbereko ilu si ma san owo-ori.

Ohun ti o dawa duro, lati ṣe gẹgẹbi a ti wi nisisiyi ni wipe, ni aseko ti nwọn ṣe Igbimọ gbẹhin yi awọn mẹta ni kosi ni ilu lara awọn mẹsan ti Igbimọ yan wipe ki nwọn lọ ro ọna ti Ijọba yio tun mu owo na gba, awọn mẹta na ni, oyinbo Aṣoju awọn Bank Ọlọla W. F. Becker, oyinbo Aṣoju awọn oyinbo Oniṣowo Ọlọla Robert F. Irving ati Ọlọla Lọya Eric O. Moore, igbakini fun aṣoju awọn ara ilu Eko.

Awọn ẹni mẹta ti a daruko wọn fun nyin pe kosi ni igbimọ ti nwọn ṣe gbẹhin yi, bẹni o si tọ wipe ki nwọn wa nibẹ gẹgẹbi a ti la a fun nyin ṣiwaju, niwọn mbẹ ni ilu oyinbo nigbana, ati pẹlu Ọlọla Gomina Graeme Thomson papa si mbẹ lọhun pẹlu nigbana, nipa eyi li a ro wipe o fi awọn ẹni mẹta na lọkan balẹ ti ko jẹki nwọn le ni ifura si wipe Ijọba le ṣe Igbimọ ọran yi lẹhin wọn lẹhin ti nwọn ti yan wọn sinu awọn ẹniti nwọn fẹ ki nwọn ṣe aṣaro titun nipa owo-ori; lẹhinna ẹwẹ nwọn ko lero wipe Ijọba le da ọran owo-ori na ṣe lẹhin Ọlọla Gomina papa, lẹhin igbati o jẹ wipe alakeso pataki lo jẹ fun ọran owo na, ti o si tun jẹ wipe, oyinbo Kingdon papa kosi ni ilẹ yi.

Ṣugbọn gbogbo nkan Ijọba ko lọ gẹgẹbi awa ti nro si, awa le ma lero wipe nigbamiran ti nwọn ba fẹ da ikan pataki kan silẹ lati ṣe bi nkan na ko ba yi ti yanri fun wọn nwọn le ṣe ohunkohun li aseko ti o ba wu wọn, nwọn ko jẹ sọ wipe awọn yio ma reti ẹnikan, tabi o di igbati ẹnikan ba de.

O dabi ẹnipe irufẹ iwa bẹ ni Ijọba lo lati fi ṣe igbimọ lẹhin awọn ẹniti a sọ wipe nwọn ko si nihin nigbati nwon yio tun da ọran owo-ori silẹ, papa Ọlọla Gomina, ẹniti a tilẹ ro wipe o yẹ ki ọran na ṣoju rẹ nigbati nwọn yio tun da silẹ ni Igbimọ.

A ti mọ wipe Gomina wa ni ile kosi ni ile, ko di ohun ti Ijọba ba fẹ ṣe lọwọ ti o ba ya wọn, ni iwọn igbati Adele rẹ ba ti wa ni ile, tabi ti Igbakẹta Gomina ba ti mbẹ ni ile pẹlu, ohun ti awọn ẹmẹwa Gomina ba ti ri ni Gomina papa ri bi ọran nkan Ijọba tilọ ni iyẹn.

Ko jọ ti awa aborikura ti o ba jẹ wipe awa li a nfẹ ṣe ohun pataki kan, bi a ko ba ri Giwa tabi baba-isalẹ nibẹ nkan na ki yio ṣe, titi di igbati oju ba pe, eyi ki iṣe eto pataki lati fi ṣe nkan, eto ti Ijọba ko si lọ bẹ arara.

Nigbati a ni Gomina Graeme Thomson ati oyinbo Kingdon kosi ni ile ninu oṣu August lati joko pẹlu igbimọ nipa ọran owo Ajulọ titun ti nwọn tun mu wa.

Ọlọla F. M. Baddeley Igbakeji rẹ mbẹ ni ile, o daju wipe ohun ti o ba ri ni Gomina ri nitoripe on lo jẹ ọtun fun Gomina, lẹhinna ẹwẹ, oyinbo Howard si mbẹ ni igbimo, o dipo Kingdom, iṣẹ ti Kingdon, ni lati ṣe, li Adele rẹ Howard ṣe, gbogbo ohunkohun ti Ijọba ba ni iṣe o lọju eyiti nwọn le reti arawọn fun, ni iwọn igbati olukuluku wọn ba ti ni adele tirẹ ọran ti buṣe.

Ṣugbọn ohun ti o yingin diẹ ṣiun nipa ti ọran owo Ajulọ ti a nsọ wipe awọn mẹta kosi ni ilu lara awọn ẹniti Igbimọ yan lati ṣe ṣawura titun miran ni wipe Ijọba i ba ṣe suru diẹ fun wọn titi nwọn yio fi de, ni iwọn igbati nwọn ti gbe iṣẹ fun wọn lati ṣe, ti a si gbọ wipe a di wọn lẹnu pe nwọn ko gbọdọ sọ bi ṣawura ti nwọn ba ṣe ba ti ri, titi nwọn yio fi pade ni igbimọ.

A si gbọ wipe ọran na jẹ ohun iyalẹnu fun Ọlọla Eric Moore nigbati o gbọ ni ilu oyinbo wipe Ijọba ṣe Igbimọ, nwọn mu ọran ofin owo Ajulọ si iwaju igbimọ, ofin na si di ohun ti o ni lati kọja, tobẹ ti o fi sọrọ nipa rẹ ni ilu oyinbo, lati fihan gbangba wipe on ko lọwọ si gbigba owo Ajulọ na, bi a tilẹ yan on sinu awọn mẹsan ti Igbimọ yan fun atunṣe owo-ori.

Nigbati Ọlọla Lọya Moore de lati ilu oyinbo, a gbọ wipe o ti kọwe si Ijọba nisisiyi lati fihan wipe on ko si ni ile nigbati nwọn ṣe Igbimọ ẹwẹ ti nwọn da ọran ofin owo Ajulọ silẹ ti nwọn si jẹki o kọja.

Bẹni a si gbọ wipe oyinbo Becker Aṣoju Bank ati oyinbo Irving Aṣoju awọn oniṣowo Kanu fun ofin na wipe o tọ o yẹ ki awọn wa ni ibẹ ni igbati ofin na yio fi kọja.

Awọn mẹtadinlogun lo wa fun Atilẹhin Ijọba lati gba owo Ajulọ na, awọn mẹwa lo si tako si ofin rẹ, orukọ wọn li eyi :—

1. Ọlọla E. H. Oke member for the Ọyọ Division.
2. Ọlọla Kitoyi Ajasa member for the Colony Division.
3. Ọlọla. G. H. Findlay Act: Resident for the Colony.
4. Ọlọla G. I. Righton Postmaster General.
5. „ C. L. Cox, Director of Public Works.
6. „ E. M. Bland, General Manager of Railway.
7. Ọlọla W. E. Hunt, Acting Secretary Southern Provinles.
8. Ọlọla K. L. Hall, Act: Deputy Chief Secretary.
9. Ọlọla The Acting Secretary for Native Affairs.
10. Ọlọla F. A. Clinch, Comptroller of Customs.
11. „ R H. W. Hughes, Director of Marine.
12. Ọlọla A. H. Hodges, Acting Treasurer.
13. „ I. B. Adam, Act: Director of Medical S.S.

14. „ J. C. Howard, Acting Attorney-General
15. „ C. W. Alexander Act : Lieut-Governor N.P.
16. Ọlọla Col : F. Jenkins „ „ S.P.
17. Ọlọla H. M. M. Moore „ Chief Secretary to the Government.

Iye awọn mẹtadinlogun ti o fi owo sọiya wipe awọn mbẹ ni atilẹhin fun Ijọba lati gba owo Ajulọ ni iwọnyi, lai ka orukọ Ọlọla Baddeley pẹlu, nitoripe on ni alakoso dipo Ọlọla Gomina, ti ko si ni ile. Iye awọn mẹwa ti ko lọwọ si sisọ ofin na ni iwọnyi :—

1. Ọlọla H. R. Routledge, Commercial member for Lagos.
2. Ọlọla L. M. Herapath, Banking member.
3. „ J. Whitfield, member for Shipping.
4. „ J. A. Caulcrick, Third Lagos member.
5. „ J. W. Speer, Commercial member for Kano.
6. Ọlọla S. H. Pearse, member for the Ẹgba Division.
7. Ọlọla S. C. Obianwu, member representing the Niger African Traders.
8. Ọlọla I. O. Mba members for the Ibo Division.
9. Ọlọla K. Ata-Amonu member for Calabar
10. C. C. Adeniyi-Jones Second Lagos member

Ninu awọn mẹtadinlogun ti a ka nisisiyi wipe awọn duro lori wipe ki Ijọba gba owo-Ajulọ, enia dudu meji pere lo mbẹ ninu won, awọn mẹdogun iyoku oyinbo ni wọn, gbogbo awọn ti a si ni nwọn jẹ oyinbo nibẹ yi, Ijọba ni nwọn nṣiṣẹ fun, tani eṣinṣin yẹ lati gbe ? Bi a tilẹ ni awọn oyinbo wọnyi njijadu ki apo Ijọba le kun nwọn ko ṣi ija na ja loju wa, ni ede ti awọn enia dudu papa, nibiti ida ba njẹ ni ida ni lati wo.

Ṣugbọn ohun ti a wa nsọ ti koi ti ye awọn Ijọba to loju wa, ni wipe li aseko ti ode oni, kosi ẹniti ko mọ wahala ti olukuluku nṣe ki nwọn to ri owo.

Ẹniti o jẹ wipe ọpọlọpọ wahala li yio ṣe ki o to le ta ọja rẹ pe oju owo tabi ki o to le ri iba ere diẹ lori rẹ.

Ẹniti o si nṣowo ti ko ni owo (*Capital*) nilẹ daradara, ki o to gboju gbaiya wipe on nṣowo, yio jẹ agbarakaka, ki ere ti o mbẹ lori ọja laseko yi to le kaju bukata ti o yẹ fun oluwarẹ lati gbọ ninu ile rẹ, sibẹsibẹ na ogunlọgọ awọn ẹlomiran ti nwọn nda owo ṣe fun arawọn lo nkigbe, wipe awọ kò kaju ilu, itumọ rẹ ni wipe ere ti awọn nri ko de ibikan fun awọn arara lati ma ṣe inawo ti o mbẹ fun olukuluku wọn.

Beni kosi ohun meji ti o nsu ẹlomiran debi owo-ṣiṣẹ (*Trading*) ni wipe nigbati o jẹ wipe ẹlomiran ti o mọ iwe ti o ni Ọgbọn ati Oye daradara to, lati fi ma fi ṣiṣẹ labẹ oyinbo tabi nibiti yio ma ri owo gere gba, ti ko si ri aye iṣẹ ti yio fi jẹ anfani iru iwe, oye ati ọgbọn ti a ni o kun inu ọpọl pọ ẹlomiran, li ero wipe nigbati o ba jaja ri ẹnikan fi elo kan bo on laṣiri lati ma ri ra ọja ta, tabi ti o ri ẹnikan ti o duro fun lati da lokowo, boya yio tun san diẹ, ṣugbọn kaka ki o san fun ọpọlọpọ enia li irufẹ bayi o tubọ nburu siwaju si ni.

A kole ka iye ọna ọpọlọpọ ti ẹlomiran ngba ki o to ri owo lati fi jẹun ati lati fi ṣe fuja ti on ki yio fi tẹ larin egbẹ larin ọgba, larin ile, larin adugbo, larin ode, larin ilu, larin aya ati larin ọmọ; ṣugbọn ti o dabi ẹnipe, irufẹ alaye bayi, ẹhin eti Ijọba lo ṣi mbọ si, boya nwọn nfi gbigbọ ṣe alaigbọ, ọkan da wa loju wipe bi o ti wu ki o ri họwu lati iye ọjọ yi ti gbogbo araiye ti ki ngbe owo-ori ati owo Ajulọ, ani ti gbogbo rogbidiyan yi ti delẹ Ijọba yio sọ wipe awọn ko kuku gbọ arara agbẹdọ, ko da wa loju, nwọn gbọ nwọn si mọ wipe a nba wọn sọ ododo ọrọ, ṣugbọn amiyan wọn ni wipe ohun ti yio ṣe tiṣe na aroye ni iyoku.

Ṣugbọn lati igbati ọran yi ti bẹrẹ lori ọran owo-ori ninu oṣu January 1927 ti a ri ka ninu Gesẹti, ti koi ti di ọran ofin owo-Ajulọ ni oṣu kẹfa ọhun ewo ni awọn ara ilu ko ṣe tan nipa ọrọ ọgbọn ori sinu iwe lati le fi yi Ijọba lọkan si ifẹ won, nibẹ kọ ni awọn ẹlomiran nsọ wipe ki Ijọba maṣe da enikan lohun ijanu ni nwọn njẹ, nibẹ kọ ni ẹlomiran nsọ wipe awọn ọmọ-ibilẹ kan, ati awọn ojoye kan ti gba, nibẹ kọ ni ẹlomiran nsọ wipe awọn ọmọ-ọba kan ti gba, ani nibẹ kọ ni ẹlomiran nsọ wipe awọn ọmọ-Ọba kan nfẹhin ge oje, iṣokun ni on ki ijẹ, ẹnyin ara Eko, ẹ dẹ oju nyin ki ẹ ri imu nyin.

Ohun ti o mu wa tun gbe ẹnu le ọran ofin owo-Ajulọ lọsẹ yi ni wipe Satide to mbọ yi ni a gbọ wipe, Ijọba yio ṣe Ajọ-Igbimọ, boya gẹgebi a ti gbọ wipe awọn Ọlọla Moore ti kọ iwe si Ijọba lati ṣe abere ẹhin ọran tun le di ohun ti nwọn o tun mu ẹnu kan ọran ofin na, ṣugbọn a fẹ ki a mọ wipe oṣu April ku oṣu meji si, ọjọ kini rẹ li Ijọba si ṣe ipinnu wipe nwọn o bẹrẹ si gba owo yi, Ọjọ na lo si wa ni igi imu yi, ewo la o ṣe a ke titi a yan titi Ijọba ko dahun, a ma si mọ wipe iṣẹ Ọlọrun o ju gbogbo rẹ lọ, ki a mai ti ja tanma ; ju gbogbo rẹ lọ, ki Ọlọrun maṣe jẹki a ri ohun ti yio mu ilu Eko yi tu ati awọn igbereko rẹ. Amin.

Emi ni tiyin nitotọ,

KẸKẸRẸ AWO.

## White's Golden Male Tonic

DOUBLE STRENGTH ).

Whenver a woman has not been in the family way for a long time, the fault is usually set down to some disease or other in her generative organs.

Now while it is true that many women suffer from disease, yet many times the fault lies with the man, owing to weakness or some other disease of the male organs of generation. White's Golden Male Tonic (Double-Strength) is calculated to give full vigour to the man, and to remove all diseases which prevent breeding. Every sensible man ought to use two bottles every month, to cure or prevent weakness of the generative organs.

Made and sold only by VICTOR WHITE, Esq.,
*The Reliable Dispensary, 41, Offin Road, Lagos.*
*N.B.*—NOT OBTAINABLE ELSEWHERE.
"Shake the Bottle."

AREMỌ FUN ỌKUNRIN.

Nigbati obinrin ko ba tete loyun, a ma nro pe ara obinrin na nikan ni arun wa. Ṣugbọn nigba pupọ ni o njẹ pe ara ọkunrin ni arun wa. Egbogi yi dara pupọ fun Arẹ, Ẹda ati gbogbo arun ti ki ẹ ki ọkunrin ṣe abiamọ.

*N.B.*—O yẹ ki gbogbo ọkunrin ma lo igo meji-meji loṣoṣu—Iṣẹ ti egbogi na nṣe ni ara ko ṣe royin.

Price TEN SHILLINGS ( 10s ) per bottle.
*Postage 2/6 extra.*

## White's Golden Female Tonic.

A splended Remedy for Female diseases such as:—Barrenness, Weakness, Painfull and Irregular, Menstruation Leucorrhœa (Whites) Cramps, Ovarian, Neuralgia, Inflammation of the Ovaries. A Tendency to Miscarriage etc, etc.

Made and sold only by VICTOR WHITE Esq.
41, Offin Road, Lagos.
*N.B :—Not obtainable elsewhere.*

GBOGBONIṢE FUN OBINRIN.

Egbogi yi dara pupọ fun Aboyun, Iju, Ẹda, Aran, Oyun ti o ba fẹ bajẹ, ati orişirişi arun mi ti ki jẹ ki obinrin bimọ.

**PRICE 10/- PER BOTTLE.**
**Postage 2/6 extra.**

WHITE'S
## WONDERFUL BRAIN TONIC

This medicine stimulates and rebuilds the brain in such a way, that the regular user is able to do many times the usual amount of Brainwork that he used to do, before using it. To Brainworkers and those who have examinations to pass, it is a boon.

Made and sold only by **SAMUEL VICTOR WHITE**, Esq.
41, OFFIN ROAD, LAGOS.
Large size 5/- per bottle. Packing and Postage 2/6 extra.
Small size, 2/6 per bottle. Packing and Postage 1/6 extra
N.B.—*Scholars should not be without it.*

EGBOGI ISỌYE.

Egbogi yi dara pupọ fun awọn ọmọ-ile-iwe, awọn ti o nfi iwe şişẹ ati gbogbo awọn ti o ba ni lati lọ fun idanwo.

*Iba şe ọmọde tabi agbalagba.*

## White's Golden Blood Restorer

*( A Native preparation for Women. )*

This medicine is an excellent remedy or Insufficiency or Loss of the monthly courses, Tumour in the Womb, False Pregnancy, Catarrh of the Womb, Various Runnings or Morbid Discharges from the Womb (especially those that are long-standing).

Sick Headaches, Dizziness, etc., etc.

Made and sold only by
VICTOR WHITE, ESQ., *Chemist,*
The Reliable Dispensary, 41, Offin Road, Lagos
"SHAKE THE BOTTLE".
Price TEN SHILLINGS ( 10/- ) per bottle.
*Packing and Postage 2/6 extra, to any part of Nigeria.*

EGBOGI ILANA ẸJẸ FUN OBINRIN.

Egbogi yi dara pupọ fun obinrin ti ko ba ri nkan oşu rẹ mọ (lalai to aseko), nkan obinrin ti ko ba pọ to. Aşẹ Ewurẹ pipọju, Ẹda ti o ba gbe Ẹyo, Oyun-koyun. Oyun ti ko ba dagba, Oyi Ẹsanri ni akoko hela, Aran ati Iju.

## HORSFIELD'S

The well known suppliers of all classes of goods under the registered Trade "ZODIAC" Mark.

Call and see our Agent and give your orders to :—

MR. MOSES O. COKER,

Port Novo Market Street, Lagos.

who has samples every mail of all the latest styles of fancy and other goods, including our REGISTERED Palm Tree and Feather Embroideries.

We supply everything.

J. J. HORSFIELD & CO.,
( Manchester ) Limited,
65, George Street,
Manchester.

## GOOD MARKET.

Gonorrhea Specific, Mol... Piles... ne, A. & D. Bula Matadi for healt... purposes : these Medicines are... heumatism Mr. H. Campos's First Class ... ne at Odunlami Street, Lagos. T... dicine Op. 37, acts like Magic : has cured m... so the Specific cases, and *will cure yours ju... many obstinate ...ist the same,* if any.

Cheap Goods ! Superior ... Quality !! Quick Fortu... ne !!!

*Cable Address* :—" W... HITE LAGOS ".

MR J. T. ... AKIREMI WHITE
... O. Box 82
20, Balo... & Breadfruit Streets
or
... n Road, Lagos.

... nts House.

... of General Lines
Export ... duce Commission Agencies
undetaken.

... ondence invited.
With ov... abian ... ars' experience in this line
of business ... Ipak...

Mr. Wh... *N.B.* ... nown connexion with reliable
Firms in ... a matter of common know-
ledge to ...

... rial is Solicited.

When replying advertisers please mention *Eko Akete*

# TO LET.

**One Splendid Pleasure Car**

No. L2754.

**Always at everybody's service at Tinubu Square.**

For Terms, Apply to

**A. B. Williams,**
14, Bishop Street, Lagos.

# ILE OWO OYINBO

# JOHN RADCLIFFE

## Ni No. 63, Ehingbeti, Eko.

———— : o : ————

Ile-owo ti o wuyi fun ọja meremere bi Ṣẹda, aṣọ Yo

ati aṣọ ti a fi ẹlẹya Oyinbo gbaleti.

-owo wa titun to

Ẹ wa bẹ orişirişi ọja wa wo

si Ile Niger ni No. 63, Ẹhingbẹti.

iliki mbẹ bi

Aṣọ lorişirişi ni aṣetejọ: aṣọ Ṣẹda ati S i sami si

awọn wọnyi jẹ eyiti awọn onibara ṣa ti nwọn si ra wọn.

ra wọn. Aṣọ lami-titi ti a npe ni Ṣantọnu nkọlu

Agbalẹtu ni gbogbo ọja wa fun didara wọn.

Pọ ọ si ni owo wọn.

(Printed at "Tika-Tore" Printing Press, 20, Market Street, Lagos, an d Publ
Adeoye Deniga at 24, Williams Street, Lagos, Writer and Lec turer.